ASOJE ORO

Olore ko ni ku, olo ore ko ni run, gbo olore ko ni fo, awo olore ko ni su, atepa aşe atepaoje ku o kuşo, kuşo ore, towo ome lo nyale olore.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

OWE YORUBA

Nibiti o wu efufu lele o ndari igbe si, ibiti o ba wu olowo eni lo nran ni lo. Afefe lo nse ori igi yeriyeri efu fe lo si nte ori agbon woroko.Aja ko' ngb gbe olore. Agutan ko gbagbe eleti bere.

VOL. XII No. 665. LAGOS, SATURDAY, MARCH 5, — MARCH, 11, 1960. KOBO MEJI (2d)


# Isele nla sele nilu Moroko Edegbeta enia rasu

**AGADIR** Işelę nla kan ja nilu Moroko tobę ti o fi ję wipe dię loku ki ilu na di ahoro. A gbǫ wipe iye awǫn enia ti wǫn rasu ninu işelę na ędęgbata ati ni alę Monday nigbati işelę na tun ja, iwǫn ędęgbętadilegba ęmi lo tun şofo danu.

Gbogbo ile awǫn alaisan lo fǫ yanyan tobę o ję wipe ode gbangba ni won tętafo egbogi iwosan si, awǫn ęgbę alanu Faranse ati ilę Amęrika wa şişę gidigidi nipa wiwa awǫn enia ti ile nlanla ya bo mǫlę.

Gbogbo ile işę ijǫba, Hospital, ilewe lo wo lulę. Ǫmǫba ilu Moroko Moalay Hassa sǫ wipe nigbati wǫn ba pari wiwa awǫn ti ogiri wo lu mǫlę tan nigbana ni awǫn o wa tun oju ilę şe, ti awǫn o si bęrę si kǫ awǫn ile tuntun.

yalenu nla kan ti o sele niti bibirin aboyun kan ti o bimo lati bi o'jo meta si abe koto isele yi ti a si hu jade laisi ipalara fun tiya-tomo ikoko ti o sese bi na.

## AWǪN ǪJǪ ISIMI FUN ǪDUN IMALE

EKO Gomina a g b a, Sir James Robertson ti paşę wipe awǫn ǫjǫ ti a tǫ si isalę nwǫnyi ni yio je ǫjǫ isimi fun gbogbo ǫdun awǫn Musulumi jake-jado ilę Nigeria ninu ǫdun 1960.

1. Ǫdun kekere (Eid-el Fitri) March 29 ati 30, 1960,
2. Ǫdun nla (Eid-el Kabir) June 6 ati 7, 1960.
3. Ǫjǫ ibi Anobi, tabi Nǫbiyu Lawani ( Mauludun Nǫbiyi ) Sept. 5th 1960.


**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branche Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGB O, OWO, ONDO, ILESH
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.

Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.


# Benson jebi Ejo Ibo

Adajo so wipe ibo ti nwǫn di fun Ogbeni Benson, eyiti o gbe de igbimo (House of Representatives) je eyiti ko ni eto si nigbati Ogbeni Daddy Onyeama nka idajo rę bo, nşe ni Ogbeni Benson fi ǫwǫ lera ti o nwo, o si fi eti ara rę gbǫ nigbati adajo so pe ǫkan ninu igbimo L.E.D.B ni Benson je

Ati pe nigbati o ri pe akoko ati dibo to oni lati kǫ iwe si wǫn pe on ko se igbimo na mo şugbon ko se bę o si ngba irinwo Poun lǫdǫ L.D.B, lǫdodun. Nigbati adajo ka idajo rę tan, o da ębi fun ǫgbęni Benson o ni ki o lo san adorin poun ati adorin sile fun Ogbeni Onitiri



T. O. S. BENSON

Adajǫ ni ki nwǫn lǫ tun ibo na di. A si gbǫ wipe Benson tun fe gbe ejǫ rę lo si Kotu kotemilǫrun, bakanna ni a gbo pe Onitiri ngbero lati gbe ęjo rę lo si Kotu arotunro nitoripe adajǫ ko gba on Onitiri si aye ti awǫn gba kuro lǫwǫ Benson laişepe awǫn tun Ibo na di.

## OLORUN MAJE KI ELERU KURO NIDI ERU RE.

Lati ǫwǫ Atopinpin.

Gegebi Owe ti a pa ni ǫse t'okǫja bayi pe Agbigbo l'oru ori oni wa aiye ori ti o ba gbe ni ki nda ęru pa ni.

Ni ǫjǫ keji omo iyale buruku yi tun se bi iya rę ti kǫ pe ki o ma şe. Nigbana ni ǫmo oba pe gbogbo awǫn Iyale ile, iyawo ati awǫn ęrubinrin lati şe abere lowo awon gegebi iwa iyawo ti ri.

Gbogbo awon dahun pe, O ję ohun iyanu nlanla fun ęnikeni ninu awǫn lati ri pe iwa iyawo yi yato si iyawo ti akoko nu wa. Nwon si so orisirişi awon. nkan ti iyawo ti o ję omo orukan ma nse, ni ohun daradara.

Inu bi ǫmǫ ǫba yi nigbati a fun ni ifo yi, to bę ge ti o fi danlyan ohun ti yio se pelu iyawo buruku ti a mu wa fun (on yi.

Ile su Ogenlo si gan, gbogbo emi rere da aşo oru bora ni iyara won. Awǫn emi buburu ti o nf ru ee osan bere [illegible]

Ni ǫganjǫ [illegible] ida yo, o si [illegible] buruku yi [illegible] o di, o si ki [illegible] ęrukunrin gbe [illegible]

(Wa yoki)

## LAGOS TOWN COUNCIL

### CONTRACT FOR SEWAGE DISPOSAL

TENDERS are hereby invited for the clearance of Nightsoil in each of the following zones of Lagos:–

ZONE 1 — Western Portion of Lagos Island, comprising Municipal Wards 'A' East, 'A' West 'B' East, and 'B' West.

ZONE 2 — The Eastern Portion of Lagos Island comprising Municipal Ward 'C' East 'C' West 'H' South and Ikoyi and the Victoria Beach Area of Municipal Ward 'G'

ZONE 3 — Lagos Mainland and Iddo Island comprising Municipal Wards 'D', 'E' East, 'E' West, 'F' North and 'F' South.

**CONDITIONS OF CONTRACT**

Tenders must provide for the clearance of Nightsoil in accordance with the following conditions:-

1. (a) In Zone 1 all sanitary pails in this Zone (including those in public latrines) totalling approximately 5,500 pails in each case, must be cleared.
   (b) In Zone 2 all Sanitary pails in this Zone (including those in public latrines) totalling approximately 4,500 pails in each case, must be cleared.
   (c) In Zone 3 all sanitary pails (including those in public latrines) which are at present serviced by the Council, totalling approximately 2,000 pails must be cleared.
2. All sanitary pails must be emptied and cleared daily, and the nightsoil therefrom must be removed by the Contractors to the Council's depots or to a specified tipping point on the foreshore.
3. The transportation of nightsoil from the Council's depots to the foreshore will be the responsibility of the Council, but the contractors will be required to tip nightsoil at the foreshore where no depots are provided.
4. Clearance of all pails must be carried out daily and the contract will provide for a penalty of five shillings per day (which will be strictly enforced) in respect of every pail not cleared.
5. Contractors must provide a labour force consisting of at least one labourer for every 40 pails to be cleared and a literate headman will be required to inspect personally every day all premises from which pails are cleared.
6. Contractors must provide drums for the collection of the nightsoil.

**PROVISION OF BOND.**

Contractors will be required to enter into a bond with the Council for payment, in the event of default, of an amount equal to ten per cent of the value of the contract for a period of six months, and persons tendering must submit with their tenders the names of two substantial bondsmen who are willing to become bound with them for the due performance of the work.

**METHOD OF TENDERING.**

1. Persons tendering must quote the amount to be charged per pail per month for the clearance of nightsoil in accordance with conditions set out above.
2. Separate tenders must be submitted for each of the three zones.
3. ALL TENDERS must be enclosed in sealed envelopes endorsed outside "TENDERS FOR SEWAGE DISPOSAL", and must be addressed to the Town Clerk, as to reach him not later than 2 p. m. on MONDAY, March 21, 1960.
4. The Council is not bound to accept the lowest or any tender.

MUNICIPAL BUILDINGS
LAGOS, February 29, 1960.

S. J. MAYAKI,
Acting Town Clerk.

## Obinrin kan ra ohun toju ko riri fun oko re.

Lọjọ Saturday 27th oṣu Feb. 1960, ariwo ta lọja Ereko. Ki ni ohun ti o de ? ohun ti a gbọ ni pe, obinrin kan wa si ọja lati ra onjẹ fun ti awẹ, ṣugbọn ẹiyẹ Agufon ni obinrin na ra gbogbo awọn ero ọja lo nkigbe ha! ha! ha!, iru ewo niyi ẹwẹ, a ha le pa agufọn ṣe awẹ dan?

Nigbati bale rẹ pada de, o yọ mọ, o wipe, kabọ o, Adigun ogo! mo ra nkan ti oju ko riri wa fun ọ loni. Ọkọ bere pe, Kini nkan na, iyawo rẹ si dahun pe Agufọn ni on ra, Ọkọ na wipe ha! ewo ni ti ẹiyẹ agufọn ẹwẹ pada lọ ma fun ẹniti o ra a lọwọ rẹ.

Bi obinrin na ti gbe ẹiyẹ na de ọja gbogbo enia bẹrẹ si woju rẹ pe, ase nṣe ni awọn lọ ji ẹiyẹ agufọn na wa ta ni ọja, oninkan si ti wa de ọja, ni awọn ba so gbagi nidi iyawo, ẹjọ rẹ si wa ni Kotu.

### MO GBỌNTAN MO MỌTAN KO JẸKI AGBỌN LORO BI OYIN

Oyin de iwaju Ẹlẹda, o ki i, o si bu ọla fun u bi o ti yẹ Ẹlẹda bere lọwọ rẹ pe, kini iṣẹ ti o fẹ ma ṣe nigbati o ba de aiye ? Oyin dahun pe, on fẹ ma ṣe oro ti a npe ni oyin igan.

Ẹlẹda sọ awọn nkan ti o ni lati tọju silẹ fun u ati ọna ti yio ma fi po wọn pọ ati akoko ti o ni lati ma jẹki o wa ni isinmi titi yio fi di oro.

Oyin fi ara balẹ lati gbọ gbogbo rẹ. Eyiti ko ye e to daradara o tun fi ọgbọn ati suru bere lọwọ Ẹlẹda. Ẹniti o fi gbogbo rẹ ye e patn.

Nigbati oyin gba gbogbo ẹkọ yi tan, o dupẹ lọwọ Ẹlẹda, o si jade kuro ni afin Ẹlẹda lati lọ palẹmọ lati wasi aiye. Ẹnikeji ti awọn iranṣẹ pe lẹhin oyin lati lọ siwaju Ẹlẹda ni agbọn.

(Iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

Polowo Oja Re Sinu Iwe Eleti-Ofe

ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O layo gbogbo irufe egbogi bee ti o ba l'ola. O dara fun lakuregbe, egbedidun, aranlatanlatan, ehin-didun, iharadi-gige, arinka-inu-egun ki ... tabi ese ro, efori, tutu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didun, oran-didun ati oristrist aisan kungekunge bawonni. Mikori wereware ti o nla, awon Yoruba npe e ni "ATA". Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BORỌKONU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (oto l'owo-oko) lati mo bi o ti ri. Kosemani mi.

The Egba Trading Aradan Stores,
16 Denton Bridge St., P. O. Box 1, Ebute-Metta.

## ỌNA MỌTO ỌJA-ỌJỌ NI YIO DE AJ ṢẸ

Irohin kan wa wipe, Ọba ilu Badagry, C. D. Akran lọ si ọna mọto ti nwọn ntọ lọ si ọja Ọjọ L..tigbo ti nwọn si ti bẹrẹ iṣẹ na, firifiri ni iṣẹ na nlọ.

Nwọn ti tẹ ọna mọto na kọja Abule Kure, nibiti nwọn gbe ọsọ Oriṣa Gumuṇr, eyiti o ku ti nwọn de Aroyadẹ ko je fọrọfẹrẹ lọ. Ogbeni Ṣogbein sọ wipe, ọna mọto na ti nwọn nte yi, ni yio jẹ ọna ero lọ si Badagry ati Ajṣẹ nile Dahomey.

A gbọ wipe bi nwọn ti ntẹ ọna na lọ si iwaju, bẹni nwọn nkun ni ọda, a si tun gbọ wipe ọgba ngbero lati tun awọn ajọ ọja ṣe kọ. Owọ wọn yio ran o.



# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos. — P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM — "ELETI - OFE LAGOS" — Phone 23370

VOL. XII. NO. 665. SATURDAY MAR 5. - MAR. 11, 1960


# Imura Sile Ati Atunse Ilu Fun Ominira.

Opọlọpọ awọn enia ni yio ti ṣe akiyesi iṣẹ ribiribi ti ijọba ilẹ Nigeria, ani, Ijọba Apapọṣe ti ilu Eko ti bẹrẹsi ṣe pẹlu inawo gìrìmọyan fun atunṣe ilu wa, ati kikọ awọn ile ala-nla alarabara ti yio gbe ilu Eko niyi gẹgẹbi Olu ilu Nigeria nigbati a ba gba ominira wa ni Ọjọ kini oṣu October, ti o mbọ yi.

Ọgunlọgọ awọn alejo ti o jẹ olowo, awọn ọjọgbọn ninu ẹkọ iwe ati awọn enia jankan-jankan ti wọn ti ngbaro ilẹ wa yi lati ilẹ America, Canada, Brazil, United Kingdom, France, Holland, Germany, Rome, Egypt ati awọn ilu bẹbẹ ni a gbọ wipe awọn mbọ wa ba wa yọ ayọ ominira na.

Nitori idi eyi, o yẹ ki a ṣe ilu wa lọṣọ, ki awọn alejo wọnyi maṣe ri aye lati yọ ṣuti ẹnu si wa. Nitorina, ẹniti o ṣe ilu London ni ọṣọ nigbati Ọba obinrin fẹ gba ade nijọsi ni a gbọ pe o mbọ wa ṣe ilu Eko ni ọṣọ, ki o le dun wo nigbati awọn alejo na ba de.


# OMORELA



is the ever-ready way to get rapid relief from Cough, Cold, Fever and all Children ailments.

This is a well tried remedy

a Chemist Product

Commercial Medicine STORES

LAGOS & IBADAN.


## Kini Itunmo Owe Yi, E Fi Ye Wa.

Olotu,

Jọwọ alagba, gẹgẹbi mo ti jẹ ọmọde ti nko si mo idi opolọpọ awọn ohun ti mo nri, inu mi yio dun bi mo ba le ri ẹniti yio ṣe itumọ re fun mi ati iru awọn ti ko mọ bi temi ti nwọn si nfẹ mọ.

Nigba gbogbo ni a ngbọ lẹnu awọn agbalagba bayi wipe;-

Onisuru lo nṣe ọkọ ọmọba Alahusa itumọ owe yi ko ye mi to, e ladi rẹ ye wa.

Emi ni,

M.S.K. Mayọ


## THANKS TO DEWITT'S PILLS

SIR,

Please allow me a space in your valuable journal to convey my best thanks to De Witt's Pills whicha lways appear ni your Eleti-Ofe.

De Witt's Pills cured my lumbago and the backache after continuous use of the Pills for two weeks on which I have spent a lot.

thanks

S.A.A. Ẹṣọ Ikoyi

18, Akinwumi Street

Yaba, Lagos, Nigeria.


## O HA DARA KI A PA AWON AGBERE OBINRIN RE BI

Olotu,

Gba mi laye lati fi ibere yi ṣiwaju awọn ọkawe rẹ bi o ba dara ki a le awọn obinrin alagbere kuro larin ilu. Eyi ni ohun ti mo ro nipa wọn.

Ko je wipe gbogbo awọn ọkunrin lo ni anfani lati ni iyawo nile, beni ko si nṣe gbogbo gbogbo ọkunrin lo je je akura. Ẹniti ko kura ni lati ni agbara. Nigbati ọkun rin ko ni iyawo ti agbara ba si gun u bi oriṣa, bi okowure ba ni owo lọwọ dajudaju yio wa awon agbere, obinrin lo lati te ifẹ ara rẹ lọrun.

Gẹgẹbi ero temi ilu ti ko ba si agbere awon alarede ni ko ni simi ijongbon ni yio si da silẹ nilu na. Idi re niyi.

Nigbati agbara ba gun ọkunrin bi oriṣa, ti ko si agbere obinrin larin ilu, ibiti ibi ti obinrin ba wa, yio wa lo ko si ni ko iyekiye lati na nitori rẹ. Nigbati okolobinrin ko ba si nile ko si aya ti obinrin ko le da nigbati ko ba ri oju oko re. Nitorina emi ṣe akiyesi wipe iranlowo ni awọn agbere obinrin awonyi nṣe fun Ijọba ati awon ara ilu pelu.

(Emi ni K. Kay, Titler)


## Kere o !

A ti ni orişirişi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdi-jẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, l'ọkunrin ati l'obinrin. ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos



Polowo Oja Re Sinu Iwe Eleti-Ofe Losose

**LAGOS RACE CLUB**

EASTER MEETING 1960

**Saturdays 2nd, 9th, 16th. Monday 18th Saturdays 23th & 30th April, and 7th May 1960.**

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course.

Note—No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Saturday 5th March, 1960.

No entry will be accepted from any horse owner unless his Stable rent in arrear is paid.

## Ijoba Egypt Gba Ki Nwon Hu Oku

EGYPT Okunrin kan, ara ile Griki lo ba ijoba ile Egypt wipe ki nwon fun on ni ase lati gbe ile ni agbegbe ilu Alexandria ni toripe on ti gbo itan wipe ni agbegbe ibi ti a wi yi gan ni nwon sin oku Alekisanda si (Alexander the great.)

Agbo wipe ijoba ile Egypt ko fe gba fun okunrin na lati sise na, nitoripe awon ara Egypt paapa ti gbo ninu itan wipe ko ose ile won ni nwon sin oku Alekisanda si.

Sugbon okunrin ara ile Griki na ti o nje Stello Komitsis tenu mo wipe, itan ti on gbo da on lojuju ose awuje lo, ko si on tase, ki nwon sa gba on laye, on yio hu oku Aleki jade.

Awon ara ile Egypt bere si se emimo si oro okunrin Griki na nitoripe nigbati Alekisanda ma ku, ko si nitosi ile Egypt rara, bawa ni oku re se wa de Alexandrie nigbeh'n nwon gba fun okunrin na nigbati aroye re poju, ki o lo hu oku alagbara nla na jade, ki nwon fi oju ri i.

### MO GBONTAN MO MO KO JEKI AGBON LORO BI OYIN

Awon Yoruba, gegebi awon Orile-Ede miran, ni opolopo nkan aroso itan wonyi ma nfun wa ni oro lopo eko ati ogbon siwaju nigbogbo igba ti a ba nka won.

Iru itan yi ni afe lati fi ayin ji ni ose yi bi ko ti se dara ki enia je mo gbo tan mo mo tan", gegebi ti agbon.

Nigbati o se, awon mejeji je ore gidigidi, ti nwon si ma mba ara won jiroro.

Nigbati o se awon meleji to Eleda lo, pe awon fe lo si aiye. Bi nwon ti de enu ona afin ti Eleda, awon iranse ti o wa nibe so fun won pe ki nwon duro.

Nigbati gbogbo awon ti o siwaju won de iwaju afin Eleda ti pari oro ti won pelu Eleda tan awon iranse so pe ki oyin lo si odo Eleda.

(Wo yoku Iju ewe keje)

**LAGOS TOWN COUNCIL**

**CLOSING OF OLOROGUN STREET, LAGOS**

It is hereby notified for general information that under section 53 of the Township Ordinance, Cap. 216. it appears to the Lagos Town Council, that the following Street is unnecessary and it is proposed to close it.

OLOROGUN STREET, LAGOS. THE PORTION BETWEEN IDOLUWO STREET AND GREAT BRIDGE STREET.

NOTICE is also given to the public that on the 1st of April, 1960, application will be made to the Minister for Lagos Affairs and Lands to close the said Street, and that any person who objects to the closing of the said Street, may, at any time not later than three days before the first of April, 1960, deliver to the undersigned at the Town Clerk's Office, Catholic Mission Street, Lagos, a notice in writing signed by him and giving his address, stating his objections to the closing of this said Street.

DATED 1st day of March, 1960.

S. J. MAYAKI
Acting Town Clerk

MUNICIPAL BUILDINGS
LAGOS, 1st March, 1960.

## Awon Alantakun Enia



A[illegible] wonyi ni nw[illegible] gbe wa ti a owo w[illegible] y', gig[illegible], bi nwon ba ja nibe koni si ipalar fun won, bonl [illegible] ko ni ja lule.

Plushes, Velvet, Velveteens, Damask & Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street. (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## Meikilisi jebi ogo-run bulala

OKE-OYA. A gbo irohin wipe okunrin ologaya kan ti ima fi igba gbogbo ye awon olopa si, bi o ba ri won ninu ... wuje a ma ru enje fun won. Nitori na, nigba gbogbo ni awon olopa ma unmu oju kuro ninu ... re.

Ni ojo kan Malam Adamu Meikilisi lo mu oti bia yo awon Yandoka si mu lo si iwaju adajo Alikali, o so fun Alikali pe iro ni, on ko mu oti, amodi onigbameji lo nyo on lenu. Alikali si koko fe gba oro re gbo ri boya iba si da sile ki o ma lo.

Şugbon, bi o ti wipe ki on soro gere lobi si agbada Alikali, ni oti bia ba bo-re si run. Alikali tawuda wipe la a ailaha illalahu!

o so fun Adamu wipe ese re di pupo.

Iwo puro fun obi pe o ko mu oti nigbati o je wipe lotito lo mu oti na. 2 O bi eebi nkan ti Olorun ko fe si agbada adajo. 3 O ba ewu Alikali je 4 O ko niwe ase lati ma mu oti Oyinbo, fun ese kokan, o jebi ogogun bulala gbogbo re je ogorin bulala.

Polowo Oja Re Sinu Iwe Eleti-Ole Losose

## Moto Meji Kolu Arawon, Dereba Salo

EKO. Dereba kan ti o nwa moto Taxi No. 4248, ni a gbo wipe, nigbati awon olopa de ibiti jamba na gbe sele nwon ba, ... o daku sinu moto re, o n nikan soso nwon ko si ri moto ti on pelu re jijo kolu ara won.

Awon olopa gbe Dereba moto na lo sile Alaisan fun itoju

Nibiti awon olopa gbe dide ti nwon si nse ... ede moto keji lo, ni nwon lo ri moto akeru kan L.B. 2870 ni oke Ebute—meta, nibiti nwon gbe duro si ni opopo Clifford Street ti ko si si eiye ninu re.

Awon olopa taku lati fi oruku dereba moto mejeji han, şugbon moto Taxi na baje pupo Akeruko si baje tobe.

Ewo olomolanke ti o gba oju ona kankan ti o si ko lati yago fun moto ti o mbo, o 'ko jamba ba onikeke basikulu, olomolanke ju keke sile, o si salo.

### ITAN BI ILE ŞE KO LATI TERIBA FUN ORUN
(Apa 2)

Lati owo Eso

Ile ati Orun bere si fa oro yi mo ara won lowo. Ile di ori eku na mo, beni Orun di mu pelu. Nibiti awon mejeji mo ara won lowo, Orun ja ori na gba, o si kunlo si ... Ile binu o nro gidigidi Orun paapa ti ko ga pupo si ile tunbo ga soke. Ile bere si ru soke lati lo gba ori eku na lowo Orun, şugbon nigbati o de ona ala ibe lo duro si ... di oni.

Bi araiye koti ri alafia, bena ni awon ara Orun pelu. Ile pinnu pe, on ko ni jeki ohun kan hu jade lori ile mo. omi ko ni ... ko. Orun paapa ni kini yoo bu ... on, oruku ... mo, ohun ko ni tan mo, irawo ko ni tan mo, aiye baje, orun bajemo.

Awon araiye wa lo si odo Orunmila ki o gba'won, kini awon yio se nipa ohun ti o dele yi? Orunmila gbe Iporun re ... le, o ...

Oro-ro-ro, Oro-ro-ro, otoṭo li a nje epa, otoṭo li a nje imumu. T'ori-t'ori ni a nfi fun oba Makio, ki o ba le fi ohun t'ori-t'ori fun ni. Ejiogbe.- Nigbayi ni awon ode aiye ko ara won lati lo de igbo Mole boya awon o ri eku miran pa ki awon le lo fi be Onimakun ki o ba le funni ni nkan ti ori fi iru.

Iyoku di ose ti o mbo.

MORTGAGES ON ALL CLASSES OF PROPERTIES
Write For Particulars:
Spencers (506)
SPENCER HOUSE, CAMBRIDGE ROAD, LONDON N.W. 6 ENGLAND

HINDU SAKKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Muhammedan ... Amulets, Vedic ... Kawachas. ... Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

... Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

... SAKKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

CARSON PAINTS AND VANISHES















SOLE AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street Lagos.

# Omo Oba binrin Yio Be Nigeria Wo



Kosi iyemeji ninu wipe Ọmọba obinrin ti iṣe aburo fun Alabyelowa ọba obinrin ilu Oyinbo yio wa bẹ ilẹ Nigeria wo ni asiko Ominira gẹgẹbi aṣoju Oba ilu Oyinbo fun ayẹyẹ ominira wa.

Ariyanjiyan yi jade lori ọrọ ti igbeyawo ọmọba na nigbati awọn ṣe ikede rẹ lọsẹ to kọja wipe boya ni yio tun le wa fun abẹwo ti ominira wa nilẹ Nigeria.

Kosi ayipada ninu wiwa rẹ o.

## ELETI-OFE D'ARABA

# Ikede Pataki

A fi wosika wa ọṣẹ yi ke si ẹnyin Ọkawe wa ti o mbẹ ni Oke-okun (Ghana) wipe ki ẹ fi orukọ awọn ọrẹ nyin ti o nka iwe irohin ni ede Yoruba ranṣẹ si wa, ki a ba le ṣe eto lati ma fi iwe irohin Eleti-Ọfẹ ranṣẹ si wọn.

Eniti o ba fi orukọ enia pataki mejila ranṣẹ si wa ti wọn si sanwo iwe wa silẹ fun ọdun kan ṣandi, a o fi iwe irohin Eleti-Ofẹ ranṣẹ si oluwarẹ fun oṣu mẹfa lọfẹ.

Olotu.

## Arún Lorun-lorun Wolu Oke-Oya

KANO. Irohin kan wa lati igboro Kano wipe iye awọn enia ti arun lọrun-lọrun nyọ lẹnu ni-sisiyi ti nwọn si mbẹ ninu ile Alaisan fẹrẹ to ẹgba enia. Ninu awọn enia nwọnyi a gbo wipe iye awọn enia ti arun ina ti pa sọrun alakeji ninu oṣu ti o kọja lọ yi jẹ mẹrinlelọgọfa enia.

Agbegbe ibiti arun na gbe nṣoro pupọ pupọ ni igboro Kano. Awọn ilu ti a gbọ wipe arun tun ti nṣ'oro bi agbọn nilẹ Bauchi Bọrọnu ati lara awọn Ṣọṣọ.

Owe Yoruba kan sọ bayi wipe " Ogun Agbọsọlẹ ko ti pa arọ, ati wipe ijafara lewu ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si awọn ilu ti a wi nwọnyi yẹ ki o lọ jẹ ajẹ-ajẹsẹlẹ rẹ lọdọ awọn Dokita tabi lodọ awọn Dokita tabi ki o lọ gun abẹrẹ ki o to wọkọ lọ.

A gbọ lẹnu awọn ero Kano wipe arun burutu yi yin ọrun ọdọmọkunrin Hausa kan tobẹ ti ọ fi jẹ wipe bi ọkunrin na ba nrin lọ, bi o ti ngbe ẹsẹ kọkan ni ọrun rẹ nyin si ẹhin




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### RECONSTRUCTION OF KANO "A" POWER STATION CIVIL WORKS

The Electricity Corporation of Nigeria invites tenders from Contractors in categories E and above of the Federal and Western Region Ministries of works Lists of contractors and categories D and above of the Northern Region Ministry of works List of Contractors for the reconstruction of Kano "A" power Station.

The work includes alterations to the fabric of the existing Power Station structure, the demolition of existing boiler foundations, the construction of new reinfoced concrete foundations, platforms, floors, cooling water towers and pond etc. etc.

The contract documents and drawings may be obtained from the undersigned on payment of a deposit of £10. Upon receipt of a bona fide tender the deposit of £10 will be refunded.

Each Tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential — Tender for Reconstruction of Kano "A" Power Station — Civil works", and must be received at the office of the Secretary, Electricity Corporation, Headquarters, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos, not later than noon on Thursday Aprril 7th 1960. Tenders received in any other manner will not be considered.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning the contract may be obtained on application to the Civil & Hydro Electric Development Engineer at this Headquarters.

C. K. O. Adenaike
AG. SECRETARY TO THE CORPORATION

Polowo Oja Re Sinu Iwe Eleti-Ofe

*Always ask for*
**'DE FACTO'**
*the bread with the appetising flavour*

## Bi ati se njuba, ki ibale se niyi

Nigba aiye Oluwo A. O. Osiga Olori ile Orunmila Adulawo,'on lo so fun awon omo ehin re bayi pe: Enikeni ninu nyin ti o ba njuba gegebi eni ti njuba yi, dajudaju ibe re yio ma se.

EDUMARE Oba Ajiki, Ajige, Oludare, Olufirejini, A bi ojo gbogbo bi odun, Adake dajo Eleburu ike, Kabiyesi Odumare mo juba.

ORUNMILA Elesin eyan, Odagba ojomu Omo Elere Omo Eleri, Enikansoso abe, Ejo meji ti nse langba - langba, Orisa fikin-fikin, Ekue sena, Omo elepo lopo ma je adin.

Bi aba si njuba, ki a mas' gbagbe awon Irunmole nwonyi, nitori awon lo mbe nidi ijuba, Oso-gidigba bi ikokun, Sango-Okunrin jangan-jangan ti iko ila ide, Esu Odara - Okunrin de de de bi orun eba ona Osetura kogbele kogbona to asiwaju to si ngbehin elebo.

### OLORUN MAJE KI ELERU KURO NIDI ERU RE
(O bere loju ewe kini)

Bi awon eni wonyi ti gbe oku yi wo inu ile awon obi re, be ni nwon ta oju kan, nwon ri iyawo won to sun si inu eru.

Awon eru yi fa iyawo nwon pada lo si ile, nwon mu le omo oba lowo. Omo pada si afin ola ti suru ati ifarada pese fun u.

Opolo ijonu ko ye wa be omo orukan wo ni ile oko re, omo yi papa si nse eto re fun opolo yi ni gbogbo igba.

Ka ma fa lo gigun, iyawo so fun oko re pe on fe ki a gbe kanga kan fun on ni ehinkunle. Ile fere maiti mo tan ti awon eru fi gbe.

Nigbati opolo tun de, omo orukan so fun ge, on fe ki opolo ati awon ebi re ko wa si inu kanga ni ehinkunle on lati ma gbe pelu on.

Lati ojo na ni opolo ti ngbe inu kanga, yato si ogodo tabi adagun omi.

Eyi ni ipari itan wa.

*Bhojsons*

Annual
**SALE**
TODAY . . .
LAST DAY OF THE BIGGEST
**BARGAINS**
OF THE YEAR

Our SUPERMARKET Reductions . . .
GREENLAND SHRIMPS (in tins) 2/-
BUITONI Products . . .
MACARONI SPAGHETTI VERMICELLI ETC.
1/- per packet
"AMOY'S" LOTUS NUTS (white) 1s
"SUN PAT" SALTED ALMONDS (in tins) 2s
MIXED (large tins) VEGETABLES 1s 9d
ALLISON'S White Wreat FLOUR 3s 6d (4 lb tins)
YELLOW CLING PEACHES (large tins 3s

Our
MANS SHOP
attractions . . .
WOOLLEN SOCKS 4s
NYLON TIES 2s 6d CAPS 6s
WOOLLEN MATERIALS 20s a yd
WOOLLEN TROUSERS 25s pr.

CAMERAS ! ! ;
many odds
CUT TO HALF PRICE

for biggest bargains . . .

*Bhojsons*
OYINGBO.
the only store open on Saturday afternoons
P.O. BOX 63, EBUTE METTA

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P. O. Box 467 Lagos Phone 2337